**Awọn èròjà inú erùpẹ̀ - Ìdánilẹ́kọ̀ọ́** – Exercice P02

# ṢIṢE ÀYẸ̀WÒ BÁTÀNÌ ERÙPẸ̀[1]

Awòrán atọ́ka *n.4- 7a-8a*

| | |
|---|---|
| ÌWÚLÒ | Ohun tí a fi n dá bátànì erùpẹ̀ mọ̀ ni bí àwọn èròjà abẹ̀mí àti àwọn èròja oúnjẹ aṣe-ilẹ̀-lóore ṣe tò tèlé ara wọn nínú erùpẹ̀. Nígbà tí àwọn ẹ̀rún erùpẹ̀ wẹẹrẹ bá ṣù pọ̀, wọ́n á dàbí i ẹ̀rún erùpẹ̀ nlá nlá, tí a mọ̀ sí ìṣùpọ̀ erùpẹ̀. Ètò èròjà inú erùpẹ̀ jẹ́ atọ́ka fún àwọn nnkan bí ìdúrógírí erùpẹ. Èyí ni agbára tí erùpẹ̀ ní láti dúró gírí nígbà tí àwọn a bá fi àwọn èròjà mìíràn sínú erùpẹ̀. |
| OHUN ÈÈLÒ |  Ṣọ́bìrì  Òrá |
| ÌGBÉSẸ̀ IṢẸ́ | 1) Fi ṣọ́bìrì bu erùpẹ̀ òkè ilẹ̀, ní ìwọ̀n ogún sẹ̀ntímítà lóòró àti ní ìbú |
| | 2) Tẹ́ òrá sórí ibi tó tẹjú  (bí àpẹẹrẹ, orí pátákó). Da erùpẹ̀ tí o bù sórí láti orí òkè tí gíga rẹ̀ kò ju ìwọ̀n sẹ̀ntịmítà kan lọ, ní ẹ̀ẹ̀méta títí tí gbogbo ìṣùpọ̀ erupẹ̀ yóò fi túká. |
| | 3) Fi ọwọ́ fọ ìṣùpọ̀ erùpẹ̀ sí wẹ́wẹ́. Ṣa èyí tí kò kúná sí apá kan. Ṣa èyí tó kúná sí apá kejì lórí ọ̀rá. To àwọn ìṣùpọ̀ erùpẹ̀ lọ́nà tí kíkì erùpẹ̀ yóò fi dọ́gba kárí gbogbo agbègbè ilẹ̀. |
| ÀNFÀÀNÍ TÓ WÀ NÍNÚ ÌLÀNÀ | Ó rọrùn láti fi ojú lásán wò ó, pẹ̀lú ìṣàmúlò irinṣẹ́ díẹ̀. Ó ṣe é ṣe láti ṣe àfiwé àwọn erùpẹ̀ tí à n lò ní oríṣiríṣI ọ̀nà. |
| IBI TÍ ÌLÀNA YÌÍ KÙ SÍ | A nílò ìwọ̀n erùpẹ̀ ti ó tó láti fi ṣe àyẹ̀wò. Ìlànà yìí dára láti lò fún àwọn erùpẹ̀ tó tutù díẹ̀. Máse lo ìlànà yìí fún àwọn erùpẹ̀ gbígbẹ àti erùpẹ̀ tó ní omi púpọ̀.. |


GLOBAL SOIL PARTNERSHIP

| ÀWỌN ÌBÉÈRÈ TÓ YẸ KÁ DÁHÙN | Kín ni àbudá (ìwọ̀n, ìrísí, líle) àwọn àkópọ̀ àti ìṣùpọ̀ erùpẹ̀. Báwo ni ó ṣe rọrùn fún omi láti gba inú erùpẹ̀ kọjá sí? N jẹ́ ìwọ́ rò pé oko ríro ni ohunkóhun ṣe pẹlú bátànì erùpẹ̀ ilẹ̀ rẹ? N jẹ́ ìwọ́ ti ṣe àkíyèsí ìyàtọ̀ kanakan láàrin orísI erùpẹ̀ àti/tàbi ọ̀ná tí a n gbà lo ilẹ̀? |
|---|---|

| ÀPẸẸRẸ ÀBÁJÁDE ÀGBÉYẸ̀WÒ | | |
|---|---|---|
| KÒ DÁRA | O DÁRA NÍWỌ̀NBA | Ó DÁRA |
| Àwọn ìsùpọ̀ ṣàkìṣákì tí ko kúná ló pọ̀ jù nínú erùpẹ̀, pẹ̀lú ihò díẹ̀ díẹ̀ tàbí kómátilẹ̀ sí ihò rárá. Èyí yóò mú àdínkù bá ìwọ̀n afẹ́fẹ́ tó wà nínú erùpẹ̀ àti pàsípààrọ̀ afẹ́fẹ́, tí yóò wá mú àkùdé bá ìdàgbàsókè àwọn irúgbìn.. | Àwọn àkópọ̀ erùpẹ̀ wà. Ṣùgbọ́n ìrísí onígun ni wọ́n ní. Ìwọ̀n wọn kò sì dọ́gba. Bátànì erùpẹ̀ tí kò dára lè má jẹ́ kí ìtàkùn irúgbìn wọ inú ilẹ̀, kí ó sì tún dàgbà dáadáa. | Ilẹ̀ yìí kún fún àwọn àkójọ erùpẹ̀ tó kúná tó sì ṣe é fọ́ si wẹ́wẹ́, tí gbogbo eteetí rẹ̀ rí roboto. Tí bátànì erùpẹ̀ bá dára, yóò erùpẹ̀ náà kò níí dì pọ̀ nígbà tí àwọn ọkọ̀ bá n gun orí ilẹ̀ náà. Ìwọ̀n afẹ́fẹ́ tó wà nínú erùpẹ̀, pàsípààrọ̀ afẹ́fẹ́ àti ìṣàn omi dára púpọ̀ nínú àwọn erùpẹ̀ yìí.. |
|  © FAO 2008 |  © FAO 2008 |  © FAO 2008 |

1 https://www.fao.org/3/i0007e/i0007e00.pdf